# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 848 LAGOS SATURDAY DECEMBER 8 — DECEMBE 14 1962 KOBỌ MEJI (2D)


## Agan Be Nile Igbimo Asofin :

# Omo Egbe Alakuko Fake Kori : Awon Omo AG Binu Jade

EKO—Agan bẹ silẹ ninu ile igbimọ Aṣofin ti Ijọba Apapọṣe ni owurọ ana nigbati gbogbo awọn aṣoju ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ Alakukọ pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) binu fi ile igbimọ na silẹ, gbogbo wọn si ko iwe wọn, nwọn si tuka mọ Alaga Igbimọ na, Alhaji Ibrahim Jalo, lori nipa ọrọ ti ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan NPC tiṣe Minisita alamojuto eto iṣẹ AJE Ijọba Apapọṣe , Alhaji Waziri Ibrahim, sọ lori gbogbo enia ti nwọn ka (Census) kakiri ilẹ Nigeria lati bi nkan oṣu keje ti nwọn ko le gbe iyọri rẹ si gbangba.

Ayiluka Eleti-Ọfẹ ni gbara ti awọn aṣoju yi ti de ile igbimọ na ni owurọ ana ni ọkan ninu won, Prince Abbey lati Owerri dide ti o sọ fun alaga igbimọ wipe awọn fẹ ki o pa iṣẹ ọjọ na ti ki awọn le fẹnu kan ọrọ ti Alhaji Waziri sọ ni ijẹrin lori awọn ENIA-KIKA (census) ki awọn le mọ ibiti awọn gbe nlọ lori ọrọ na. Alaga na kọ jalẹ, eleyi ni o mu ki gbogbo wọn tuka mọ lori.

Gbara ti nwọn ti jade ni olukuluku ẹgbẹ oṣelu ti o wa ninu ile Igbimọ na lọ ṣe ipade ninu eyiti nwọn ṣe ipinnu nla kan wipe awọn ko ni igbẹkẹle lori iṣẹ Minisita Alhaji Waziri pẹlu Oyinbo akania, Ọgbẹni Warren mọ. Awọn fẹ ki Ijọba wa Oyinbo na kuro nilu ni kiakia. Bi bẹ kọ awọn ko ni pada sile igbimọ na. Ọkan ninu awọn alayọnusọ Minisita ẹgbẹ ọmọ Alakukọ (NCNC) ti o fẹ da si, nwọn ni ki o fi tirẹ ṣe tirẹ.

---

## OGBENI MADOJUTOLA PA ITAN FUN OLOYE OJIKUTU :

# O Ni Oko-Eru Ni O Fe Ko Awon Lo

Eyi ni esi ọrọ Oloye Yẹkinni Ojikutu ti awọn ọmọ ẹgbẹ alapata ẹran l'Eko sọ wipe awọn rọ loye ati pe ki o ko gbogbo iwe ẹgbẹ wa fun Olori titun, Ọgbẹni Lawani Madojutọla.

Oloye Ojikutu, o ti sọ oko si wa, o si yẹ ki awa na sọ ogalutu lu ẹ ṣugbọn a ko ni ṣe bẹ, idi ọrọ ni ao la ye gbogbo enyin ti ẹ nka ọrọ wa na.

Oloye Ojikutu si wa ni ile iwe nigbati a da ẹgbẹ alapata ẹran silẹ l'Eko ; LAGOS AND EBUTE-METTA BUTCHERS' UNION ni a npe orukọ ẹgbẹ na Ologbe SUNMỌNU AILARA ni Daddy Alaja Street ni Oke-Arin ni baba ẹgbẹ na pẹlu Ọgbẹni B.B. Salami ti a fi ṣe akọwe.

Lẹhin igbati iṣẹ apata ẹran di gbẹfẹ ni iwọ Oloye Ojikutu to da ẹgbẹ tirẹ silẹ ti o si sọ ni LAGOS WHOLESALE and RETAIL BUTCHERS' UNION. Ẹgbẹ agba ni tiwa si jẹ si ti Oloye Ojikutu yi. Ẹgbẹ wa na li o si dide si ọrọ rogbodiyan iye bayi (Food control) ni ẹni lati ta ẹran de ti nwọn ṣe lofin ni ọdun 1942 nigba OGUN AGBAIYE.


(Wo iyoku loju ewe keji)


## Nwon Si Gbongan Glover Lana

EKO —Ile apẹjo awọn ara Eko ti gbogbo nyin mọ pipe rẹ ni Glover Memorial Hall ti nwọn ti tun tun kọ ni nwọn pe Gomina-agba Ọlọla Dokita Nnamidi Azikiwe wipe ki o wa ṣi ni ana ọjọ Jimọ loju gbogbo awọn enia pataki pataki lọkunrin ati lobinrin.

Ọkẹ-mẹta-o-le-ọdẹgba-a Jọ ponun (£75,000) ni nwọn fi kọ ile gbọngan na, o si gba ẹgbẹdọgbọn enia, yatọ si ile ti atijọ, oriṣiṣi nkan mere-mere ni nwọn fi si ile tuntun na.

Ọlọla Dokita Kofoworọla Abayọmi tiṣe olori awọn olutọju ile na ni o fi kọkọrọ iyebiye le Gomina—agba na lọwọ ni irọlẹ ana pe ki o fi si ile na.

## Ogbeni Madojutola Pa Itan Fun Oloye Ojikutu :

# O Ni O ko Eru Ni O Fe Ko Awon Lo

( O bẹrẹ loju ewe kini )

Capt. Pullen, alaṣẹ ọja ni kọbọ meje ati abọ (7 1/2d) ni a ni lati ma ta iwọn ẹran kan laisi egun nibẹ. A ni kole pe wa rara, a fi ki a ta iwọn kan ni kọbọ mewa ati abọ (10 1/2d) la si egungun. Nigbana ni iwọ Oloye Yẹki ni Ojikutu wa faramọ ti Oyinbo na. O gbagbe wipe ọpa agbeleka tẹhin loju. O wa ni anfani lati tako ẹgbẹ awọn agbalagba. Ọrọ na dogun o dọdẹ.

Ni asiko na gbogbo isọ alapata ẹran tu nigbati gbogbo awọn alapata ẹran tẹ di ẹlẹwọn tan. Ọmọ inu isọ tirẹ paapa ni adajọ kan sọ si ẹwọn (a ko fẹ daruko ọkunrin na sinu iwe yi) pẹlu iṣẹ aṣe-kara. Nigbana iwọ na wa ri wipe nkan ti o nṣe ko dara. Lẹhin eyi ni o wa dide, ti o kesi awa ẹgbẹ agbalagba, awọn bi Ọgbẹni Madojutọla, Salami Ladọtun, Olori Adeyẹmọ ni ita Faji, Alhaji R ji ni ita Faji ati Alhaji Alabi Ilọrin wipe agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ tuntun wọ, ki nwọn jọwọ gba ọ, ki nwọn lọ ba Oyinbo alaṣẹ ọja yi sọrọ wipe ki o tun ofin na ṣe. Ṣe eleyi ni iwọ Oloye Ojikutu npe ni nwọn wa tuba fun ọ?

Oloye Ojikutu kinni o ndun ọ ti o tun nsọ oko ebu si wa? Awa kiṣe amukun mẹkọ rara; a si kiṣe alaimọre. O ri bẹ loju tirẹ ni.

Nitotọ a pin ẹran ṣugbọn gbogbo anfani ibẹ iwọ ni o njẹ. Ṣebi o tilẹ ni iye ẹran ti a pin lọjọ na lọhun ki o to ọ fi adọta ẹran kun lai sọ fun awa Jaaman rara. Nkan ti o fọ ẹgbẹ mọ ọ lori niyi ni akọkọ. A fẹ ki o ṣe iranti nkan ti o pa wa pọ ni 1954 A ko ti fẹ fẹnu kan iyẹn nisisiyi rara

Jamba nla onile taji ti o wi ninu ọrọ rẹ lọsẹ ti o kọja, owe na tirẹ ni o. A ko fẹ ki o tun ko wa lọ si oko-ẹru lẹkeji ni awa Alapata fi kọ ẹ lolori wa, a si fẹ ki o ko gbogbo ẹru iwe wa fun wa.

A duro nihin, a si nreti esi rẹ ni ọsẹ ti mbọ ki a to afọgba ayanga mọ ẹ lori.

## E SORO NA SOKE!



Alagba ẹ sọrọ na soke ki gbogbo wa gbọ! Se ko nṣe ọrọ lori awọn enia ti a ka ti ko ti yanju ni? Aworan oke yi ni ti igbati awọn Ọlọla Tafawa Balewa ati Ahmadu Bello nfi ẹrọ gbohungbohun (telephone) ṣe ere mbiti awọn Gẹsi pate ọja si laipe yi l'Eko.

## Arufin Kan Fe Pa Adajo Kotu Ilu Ibo

IKOT-Ekpene — Gbogbo awọn ero ti o wa si kotu awọn ọlọpa ni ilu ti nwọn npe ni Ikọtẹ-Ẹpẹni ni nwọn yanu nigbati nwọn ri Ọgbẹni E. O. Igboku tiṣe adajọ Kotu na, ti o sare, ti o fi ọwọ fa eti nigbati ọdaran kan ti nwọn mu wa si iwaju rẹ fa igudan ada yọ, ti o nsare bọ wa bo o mọ ori ijoko rẹ.

Onirohin wa ni awọn ọlọpa ni arufin na ti oruko rẹ njẹ Sunday Ugbugho jade, nwọn ni ki o wa sọ tẹnu rẹ ki adajọ to sa konko mọ ọ. Ọrọ ẹjọ rẹ na ni nwọn nro lọwọ ki o to fa igudan yọ, ti o fẹ lọ bẹ ori adajọ silẹ ki adajọ na to taju kan an, ti o ri ni o ba sa wọle ti o si ti ilẹkun mọri patapata.

O to awọn ọlọpa mejila ti nwọn gbogbo arufin na mu papanko lenu ọn iyara adajọ ki nwọn to mu lọ si itimọle.

## Ikuku Npa Awon Enia Ni Ilu Oyinbo

LONDON—Waya irohin kan tẹ wa lọwọ lati ilu Oyinbo ninu eyiti onirohin wa sọ wipe ikuku (fog) ti o bẹrẹ ni ijẹjẹ ti pa ọgọọlọgọ enia ilọkunrin ati lobinrin, lọmọde lagba, ọpọlọpọ awọn ọmọ-iwe ni nwọn ni lati joko silẹ nigbati mọto ati ọkọ ti nko wọn lọ ko riran rara loju ọna.

Awọn onilu ilu Oyinbo ni awọn ti ri iru agbako ikuku oni-jamba bayi to ọdun 1952, ọdun kẹwa sẹhin, ti o si pa bi ẹgbaji (4,000) enia. Nwọn ni awọn ko ti mọ iye enia ti eleyi na yio pa.

**AYILUKA Eleti-Ofe lo si ile Igbimo awon Asofin l'Eko, ka irohin soki ti o mu bo wa loju ewe kejo iwe yi pelu awon oro re miran loju ewe karun.**

# Alhaji Ju Alhaji Kan Sewon Odun Meji

KANO— Alhaji Muhammadu Dodo, adajọ kẹtu ilu Kano da ẹjọ ẹwọn ọdun meji fun Alhaji Shehu Maimota, oga ile iṣẹ Ijọba Ibilẹ Kano ti awọn Ọlọpa fi sun ẹsun wipe o gba owo riba lọwọ ẹnikan nigba kan.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ba ọdaran Alhaji ro ni wipe on ni ọga ile iṣẹ Ijọba Ibilẹ Kano nibiti nwọn ti nyan iṣẹ fun awọn kọntrakitọ, ti mba wọn ṣe alagbaṣe iṣẹ. Nwọn ni ki o to gbe iṣẹ fun Ọgbẹni kọntirakitọ kan ti nwọn npe ni Alhaji Sanni Kwangila, o gba ẹdẹgbẹrin pọnun (£700) lọwọ rẹ.

Nigbati ọdaran yi ro ẹjọ tirẹ, o ni ọrọ yi kiṣe ẹbi ti on rara, Ọba Kano ti ni o fun on laṣẹ wipe ki on gba owo na lọwọ kọntirakitọ yi ki awọn fi ra nkan ẹṣọ sinu ile Ijọba ti awọn nkọ fun awọn oṣiṣẹ.

Asoju Ọba Kano, ti nwọn nran wa si Kotu nigbati nwọn nro ẹjọ na ni irọ ni. O ni Ọba Kano ko mọ nkankan nipa rẹ rara.

# Ijoba Ni Ki Oku Wa San Owo-Ori

EKO— Oku ki san owo posi ni a ti ngbọ ri ṣugbọn awọn alakoso Ijọba Apapọṣe ilu wa l'Eko ni bẹkọ, nwọn si ti tẹ ofin tuntun kan sita ti nwọn fẹ fi ọwọ si ninu ile igbimọ awọn aṣofin ti nwọn fẹ bẹrẹ ninu ọsẹ yi wipe oku ti o ba ti ku ni lati san owo-ori.

Ayiluka Eleti-Ọfẹ ti o fi oju agba wo ofin owo-ori tuntun na ti Ijọba fẹ bẹrẹ lati ma lo ninu ọdun ti mbọ ni Ofin na fa kiki, ko si gba gbẹrẹ rara fun awọn ti ko fẹ owo-ori san rara.

Iwe ofin na ni awọn babansinku ni lati san owo-ori enikẹni ti o ba ku. Nwọn ni gbogbo eyi ti ko san nigbati oku na wa laiye ti o wa loyẹ ni nwọn ni lati san fun un.

Iwe ofin na fẹnu ba ọrọ awọn alarede ti nwọn ba ti kọ ara wọn silẹ tabi awọn ilemosu pe awọn a ro ti wọn ṣe, ṣugbọn nwọn ni lati san owo-ori.

## Bisobu Agba Pade Agbako: Ijo Ilaro Ko Sosi Sile

ILARO—Gbogbo awọn agba Ijọ Ṣọṣi ti nwọn npe ni Dhrist Church ati awọn ọmọwewẹ Ijọ Ṣọṣi na ni nwọn binu kọ Ṣọṣi silẹ fun Bisọbu—agba Ẹni-ọwọ A.W. Howells nitori alufa a ọn ti o gbe Kuro lọdọ awọn ni ainidi, gbogbo wọn ko si wa ibi isin ikore ti nwọn ṣe ni Ṣọṣi ni ijeje.

(Wo yoku loju ewe k-

CARSON PAINTS AND VANISHES



SOLE AGENT.
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28 Balogun Street, Lagos.



# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABELS & TELGRAME

28 Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI—ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 468 Phone 23370

VOL XIV No 848, SATURDAY. DEC. 8, - DEC. 14, 196


## Atunka Awon Enia

Bi eti ko ba gbọ yinkin inu ko ni bajẹ—Owe awọn baba wa ni ilẹ Yoruba niyi, ṣugbọn ọrọ na ba ọrọ awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe wa mu lori ọrọ alaye ti Alhaji Waziri Ibrahim, Minisita alamojuto e t o nkan aje to ṣe lori awọn enia ti nwọn ti ka ka-kiri gbo gbo ilẹ Nigeria ti nwọn k ọ lati gbe iyọri r ẹ jade sita fun gbogbo wa.

Ninu ile Igbimọ a w ọ n asofin l'Eko ni ijẹrin, Minisita na sọ f u n gbogbo agbaiye wipe gbigbe ti awọn ko gbe iyọri g b o g b o ti awọn k a iye awọn enia na si jade ko nṣe ẹbi awọn rara bikoṣe ti awọn aladugbo wa ni Ipinlẹ Ila Orun ni ilu Ibo.

Nwọn ni awọn ilu bi Awka, Brass mọ agbegbe Opobo nṣe ni nwọn mbu enia mọ enia ti nwọn ka nitorina nwọn ni lati tun awọn enia ilu ka ni.

Awa oniwe irohin "Eleti—Ọfẹ" lati bi oṣu melo kan ti a ti ri wipe ọrọ awọn enia ti nwọn ka na di koko ni a ti ntẹ mọ gbogbo ẹnyin enia wa leti, o dabi ẹnipe awọn kan fẹ ṣe aidara nipa rẹ. Awa k o sọ wipe Ipinlẹ kan ni o jebi ọrọ na, ṣugbọn on a fẹ fi setigbọ yin ni wipe ki ẹ maṣe ọrọ na ni "ẹniti o ba ka mi ka igba iya rẹ," ki ẹ jẹki nwọn ka ọ tọmọ-tọmọ ati tọkọ tọkọ.

## Abosi Leyi!

Laipẹ yi, nigbati gbogbo awọn ara ilu Eko fẹ ... si ile igbimọ minisifa Eko ni a ri ti awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti nwọn npe ni Alaake (NPC) ti Ọlọla Amadu Bello, Sardauna Sokoto nṣe Olori wọn yan obinrin ka n jade wipe ki awọn ọkunrin ati obinrin dibo fun ki o le wọ ile Igbimọ.

Nkan ti a fẹ fi ye ẹnyin ọkawe wa nipa ọ r ọ yi ni anfani idibo ti awọn ọmọ ẹgbẹ yi kọ f u n awọn obinrin wọn patapata ni Oke Ọya nibiti nwọn gbe ti da ẹgbẹ yi silẹ. Nw n n i obinrin Imale k i sọrọ si nkan ilu.

Bi o ba jẹ beni, kinni ṣe ti nwọn fi sọ wipe k i awọn obinrin Imale Eko dibo fun awọn tabi Ọlọrun Imale t'Eko yatọ, ti Oke Ọya y a Mẹdina ninu adinni?

Bi ọrọ ko ba fẹ dabi ọrọ alabosi, akoko to ki a fun awọn gbogbo obinrin ilu Oke Ọya ni Ipinlẹ Ariwa na laye ki awọn na le ma dibo nigbakugba ti asiko lati dibo ba de.

Adinni awọn ara Oke Ọya yi ko to ti awọn ilu Imale bi ti ilu Larubawa (United Arab Republic), Jordan, Pakistan ati Turkey rara, sibẹsibẹ gbogbo awọn ọmọ wọn obinrin ati iyawo wọn lo njade lati dibo. Bi a ba kọ jati ṣe eyi alabosi ni wa.

## Iwe Si Olotu

## E Wo Se Fun Wa

E jọwọ ẹ ba wa kesi awọn Alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn gbe ofin nla le awọn ti o nfi iṣe pulu (Pools) ṣe iṣẹ lori ki nwọn wo ọrọ na ṣe fun wọn.

Owo ti nwọn ni ki nwọn ma wa fi gba iwe-aṣẹ ti pọ pupọju. Owo ko si ni ita tobẹ mọ, awọn enia ko si ta tẹtẹ-bọlu to bẹ mọ.

Ti a w ọ n Alamojuto iṣẹ Ijọba ko ba fẹ ki a w ọ n ọmọ jaguda pọ n i l u, ki nwọn ro ọrọ na ṣe o.

Emi ni,

A. Alamu

Mushin

## Eka Irohin AYILUKA NI Oju ewe karun osose Ati Oro Ologbon Pelu Oye ninu Iwe Eleti-Ofe


## YOU WILL NEVER GO WRONG

When you select and buy any of the following :-

100 o/o WOOL FANCY WORSTED SUITINGS
(Made in England)
(guaranteed against SUN, AIR & RAIN)
BEST QUALITY GERMAN VELVET
(Various attractive designs & colours)
unbeatable quality & design.
HEAVY COTTON GUIPURE ALLOVER (LACE)

HIGH QUALITY FANCY FURNISHING MATERIALS
(In Art Silk) various design & colours
Price to suit all pockets

HEAVY ART SILK BROCADE
in various colours
(OKUNOWO SPECIAL DESIGN)

**ONLY FROM**

**THE HOUSE QUALITY & DURABILITY**

**OKUNOWO BROTHERS**

63, Massey Street, Faji, Lagos.
Telephone: 23114.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

( LATI ỌWỌ AYILUKA )

## Awon "Adele"

Ni ọsẹ ti o kọja mo sọ fun yin wipe awọn "Adele" alamojuto iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Ila Orun (Commissioners) ti a fi pajawiri yan ti npalẹ mọ diẹ diẹ lati pada si ile wọn nitoripe isẹ wọn ṣẹ npari diẹ diẹ. Ẹnyin ọrẹ mi, o yẹ ki a yin awọn "Adele" wa na nitoripe nwọn ṣe iṣẹ kara-kara fun asiko diẹ ti nwọn ṣe alamojuto iṣẹ ijọba ipinlẹ na.

Mo mọ diẹ ninu awọn enia mọkandinlogun na ti nwọn yan si ipo "adele" na bi ẹniti o mọ owo, mo si mọ wipe nwọn ki ṣe ọlẹ enia rara. Mo mọ awọn bi Oloye Jas. Ọla. Fagbemi, alamojuto eto ilẹ ati ilu tuntun; Ọmọba Adeleke Ademuluyi, alamojuto nkan ọgbin ati isura; Ọgbẹni V. Owolabi Ẹsan, alamojuto eto inawo, Ọgbẹni TEA Saluba, alamojuto eto ẹkọ, Oloye S.L. Edu ("Baba Abiye") alamojuto eto ilera ati Ọgbẹni Ade. Thanni tiṣe akede Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na.

Ki a wa pada si ọdọ awọn ọba ti nwọn ko gbe wahala iṣẹ pataki le lọwọ sugbọn ti nwọn wa ni po olubadamọran, awọn bi Ọba Akinyẹle, Olubadan ati Ọba Ibinni, Akenzua Keji. Mo tilẹ gbọ pe Ọba Akenzua na ṣe bẹbẹ ni ilu Asaba laipẹ yi, o fun awọn ara ilu na ni ọgọrun pọnun fun omi- ẹrọ ti awọn ara ilu na fẹ fi owo ara wọn ra bi Ijọba ko bi le ra omi-ẹrọ fun awọn. Mo gbọ wip Oloye Osadebey paapa na ṣe bẹ pẹlu. Dennis, o ṣe pupọ orisa ilu baba rẹ yio gbe ọ o.

### AYARA-BI-ASA



Aworan yi ni ti awọn ọmọbinrin ilu Gẹsi merin ti nwọn lọ ṣe aṣoju ilu wọn ninu ere agbaiye ti nwọn ṣọṣẹ ṣe ni ilu Australia. Onirohin wa ni awọn ọmọbinrin na le yara sare bi aṣa.

### Alapata De !

Ninu ọsẹ yi iwe meji ni mo ri gba lati ọdọ awọn ti o nka iwe ti mo nkọ sinu ELETI—ỌF ni ọsọsẹ. Ekinni lati ọdọ Ọgbẹni alapata kan, ekeji lati ọdọ olukọni kan ti o pe ara rẹ ni Tiṣa nipa awọn enia Nigeria ti nwọn fẹ tun ka.

Ẹnyin ara mi, iwe ti mo ri gba lati ọdọ ẹnikan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ alapata ẹran ilu Eko yi ni mo ti fẹ junu ṣugbọn mo wa ri wipe itan fun oju ọla ma mbẹ ninu ebu nigbamiran, nitoripe nigbagbogbo ni mo ti nma ngbọ ti awon orogun lobinrin ti ma bu ara wọn, ti nwọn si nma nsọ itan bi bale wọn ti fẹ ẹnikan dele si ara wọn.

Iwe ti alapata na kọ niyi : "Ayiluka tabi ki ni o pe ara rẹ ? O ni Oloye Ojikutu ni o sọ aiye awa alapata dẹrọ lori iṣẹ ẹran. Mo fẹ sọ fun ọ wipe ọrọ ti o ko mọ idi rẹ ni o nda si.

### Ase Onikunmo

"O ni Oloye Ojikutu sọ aiye awa alapata dẹrọ fun wa. Irọ ni eleyi, mo fẹ fi nkankan ye ọ nipa rẹ, iyen ni wipe gbogbo bi a ti nsa, ti a nki i, o ko mọ wipe gbogbo awa ọdọmọde ti a nṣe iṣẹ apata ẹran lẹhin Oloye Ojikutu ni a wa, ṣugbọn gẹgẹbi Olori nigbati aiye awa alapata ẹran l'Eko le, ti nwọn nko wa da sẹwọn bi ọmọ jaguda o dabi ẹni wipe Oloye na fẹ ju wa silẹ. Ki a sọrọ si ibiti ọrọ gbe wa, o ju wa silẹ patapata.

"Aṣẹ-Onikumọ paapa nkọ ? Ẹnikan ki jẹ awa de! Nigbati a fi Oloye Ojikutu ṣe Olori a tun yan awon Oloye miran pẹlu rẹ ṣugbọn gbogbo igba ni o mọ nyọ aṣẹ jadeni apo ara rẹ ti awọn oloye yoku ko ni mọ rara. Iye ti nwọn pin ẹran pipa si kọ ni o wa loni, a si mọ ẹniti o bukun iye ẹran na.

"Iwọ Ayiluka ni Oloye Ojikutu ti sọ aiye awa alapata ọmọ Ibadan dẹrọ ati pe gbogbo wa ti a ti jẹ gbese ni a nrin falala ni a nyan, ti a si nkọle mọle. Ọrọ yi ko ri bẹ, olukulukù ni o mọ ibiti bata gbe nta on lẹsẹ. Gbogbo aṣọ kọ ni enia ni lati sa ninu orun. O yẹ ki Oloye Yẹkini Ojikutu na si fi aye silẹ fun awọn ẹlomiran ki nwọn si lo asiko wọn bi olori alapata ẹran na ki a wo na.

Emi ni,
Ọmọ Oke'badan"

"Ọmọ Oke'badan" o ṣe pupọ pẹlu alaye rẹ, ko si nkan ti o nle ti ki rọ, boya emi Ayiluka ni ma ba nyin pari ede aiyede yi ki ọdun Keresimesi to de.

### Atunka Enia

Iwe keji ti mo ri gba lati ọdọ "Tiṣa" kan lati Ikorodu niyi lori awọn enia ti nwọn ni nwọn fẹ tun ka kakiri ilu Nigeria.

"Ayiluka, ọrọ nyin ṣẹ lori awọn enia ti nwọn ti fi igba kan ka ti a ko gbọ iye ti nwọn ka wọn si, ati tun gbọ wipe nwọn tun ngbero lati tun wa ka. Nibo ni nwọn ti fẹ ri owo iyebiye ti nwọn tun fẹ na lori enia kika na?

"Kiloṣe ti awọn aṣoju wa na fẹ lati ma fi ọbọ lo wa bayi? A gbọ wipe awọn kan ni Ipinlẹ kan ni o dabi ẹnipe nwọn fẹ bu mọ awọn enia ti nwọn ka lọdọ ti wọn, eyi lo si jẹ ki nwọn gbe iwe ikania na ti sibi kan. Ẹ jọwọ Ayiluka, ẹ maṣe fi ọrọ na di wa leti o. Emi ni "Tiṣa, Ita Ẹlẹwa, Ikorodu."

# Bisobu-Agba Nfe Iranlowo



Aworan oke yi ni ti Eni-owo Oliver Green-Wilkinson, bisobu agba ti Central Africa nibi ipade kan ti o ti nsoro wipe on fe iranlowo lati odo awon ojise Olorun, on si tun nwa awon enia dudu meji ti nwon y o j e igba keji fun on lati ma se ise Olorun.

Lati bi odun mokanla ti bisobu agba yi ti de ile enia dudu wahala bi yio ti se ri owo ko ile Olorun si ni o mba kiri ni ilu Afirika na.

## Ijoba Apapose Ngbero Lati Tun Awon Enia Ka Ni Nigeria

EKO-Ọrọ bẹhin yọ a w ọ n alamojuto Ijọba Apapọse tun ngba ero lati tun awọn enia ka kakiri gbogbo ilẹ Nigeria d i p o eyiti n w ọ n ti ka lati bi nkan oṣu meje ti nwọn ko le gbe iyọri enia kika na jade di ọjọ oni.

Minisita alamojuto nkan aje, Alhaji W a z i r i Ibrahim fi eyi ye awọn oniwe irohin nigbati o n b a w ọ n sọrọ laipẹ y i n k a n ti o fa a ti a w ọ n k o ti le g b e iyọri awọn enia ti nwọn ka na jade.

(Wo yoku loju ewe8)

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

### Bisobu A g b a

Minisita na ni gbogbo idiwọ na lati ọ d ọ awọn alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ati Ila Orun ni o tiwa Ila Oruni o tiwa nitoripe a w ọ n alamojuto I j ọ b a Ipinlẹ Ariwa ni Oke Ari-Ọya lọhun ti ṣe eto enia kika ti wọn ti pẹ.

Onirohin wa f i ye w a w i p e n w ọ n ni lati k o awọn ọlọpa wa lati Abẹokuta nigbati ọrọ na fẹ bi-ge bi adubi nitori Alufa S. O. Osiyale ti nwọn mu kuro ni Ilaro lọ si Ijẹbu Mushin.

A gbọ wipe ede aiyede n a bẹrẹ lori ọrọ tiṣa agba kan ti o yawo lọdọ awọn ijọ ra moto-ayọkẹlẹ kan fun ọna iṣẹ rẹ: awọn kan ni Alu-fa Osiyale lodi si ọ r ọ yi nitoripe ko fẹ ki a na owo ṣọṣi ni inakuna rara.

Awọn agbalagba ti nwọn ko fẹ ki ọrọ na da nkan silẹ, awọn bi Ọba Adeṣina Olubara lati Abẹokuta dide si ọrọ na sugbọn ko ti loju ra-ra. O ju ẹgbaji awọn enia lọ ti nwọn fi aake kọri wipe awọn ko fẹ alufa tuntun, Odunuga, ti nwọn mu wa fun awọn.

Gbogbo awọn enia i j ọ Ṣọṣi Ilaro na si ti kọwe ẹbẹ si Bişọbu Olori gbogbo ijọ awọn CMS., Archbishop Patterson wipe ki o ba awọn ri si ọrọ na nitoripe Bişọbu Howells ko fẹ mọ nkankan rara nipa rẹ, awọn fi ọ r ọ na sun titi o ti su awọn.

**HAVE YOU exchanged your**
OLD WEST AFRICAN COINS
**for Nigerian Money ?**
FREE EXCHANGE at banks e n d s on
**December 31st, 1962.**

# British Colleges Will Take More Nigerian Students

LONDON — British universities, colleges and hospitals are ready to take more Nigerian students in a wide range of fields of higher education. That is the cheerful news which Chief Akitoye Coker, Agents-General for Western Nigeria, is hearing during his week's tour of provincial centres in Britain where Nigerian Students are being trained.

"I am reall heartened by the Sympathetic response I have received to requests for more places in British, colleges and universities," he told our special correspondent yesterday.

"We look to Britain to help us in providing higher education for our students. So far I am delighted at the response we have recevied," he declared.

In the first day and a half of his tour the Agent General has already had promises that the Colleges of Technology and Commerce in Leeds, Yorkshire, will take more students, that the Faculty of Medicine at Leeds University will accept a small but regular quota of suitably qualified medical students, and that University Departments of Engineering and social Studies will also concider allocating regular places to Western Nigeria Sudents.

There are already more than 100 students from Nigeria in Leeds and the Agents—General heard excellent reports of their work.

"The Principal of the Leeds College of Technology told me that our students have achieved good results and are very enthusiastic. He said he would welcome many more provided of course that their qualifications were good. This means that we shall have more people trained in a variety of fields including printing, science, food technology and dietetics," said Chief Coker.

He has received similar promises from the Leeds College of Commerce and plans to visit a number of hospitals in thedistrict there Nigerian nurses are training.

"Everywhere I shall be enquiring into the exact standards of entry into the colleges and universities so that we can be certain of sending students who will complete their courses successfully," he said.

Chief Coker is being accompanied by two members from his Staff. Their tour will continue in York, Bradford and Huddersfield, Manchester, Nottingham and Birmingham.


**Read and Advertise In Eleti – Ofe**


## RT. HON. DUNCAN SANDYS .C., M.P.



The Rt. Hon. Duncan Sandys, P.C., M.P. Secretary of State for Commonwealth Relations and Secretary of State for the Colonies, was born on January 24th, 1908. Educated at Eton and Magdalen College, Oxford, where he graduated M.A., he entered the Diplomatic Service in 1930.


**Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

(63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfactione Guaranteed.

Eleti-Ofe D'araba

The advanced quality of the Fiat "sixes"

FIAT 2300 and FIAT 1800 B

more power, elegance, comfort, disc brakes



The Fiat 2300

PRICES

| | 2300 Ex Lagos | 2300 Ex Turin | 1800 B Ex Lagos | 1800 B Ex Turin |
|---|---|---|---|---|
| STANDARD SALOON | £1,380 | £698 | £1,250 | £638 |
| STATION WAGON | £1,530 | £775 | £1,380 | £710 |
| SPECIAL SEDAN | £1,730 | £845 | | |

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.) IBADAN KANO KADUNA JOS PORT HACOURT ABA.

## Irohin Soki

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

### Olopade

Mo Ayiluka de ile Igbimọ awọn aṣofin ilẹ wa ni ijerin lati gbọ ọrọ ofin tuntun ti nwọn fẹ ṣe nibẹ lori awọn ọmọ wa ti nwọn nṣe iṣẹ agbejọro ti ẹ npe ni lọya (Lawyer), ṣugbọn nigbati mo de ibẹ ọrọ awọn enia ti nwọn ti fi igbakan ka (Census) ti nwọn ko le gbe ayọ isi rẹ jade nimo ba Alhaji Waziri Ibrahim, Minisita alamojuto iṣẹ aje, ni o mba aṣoju Igbimọ na sọrọ lọwọ lori gbogbo awọn enia ti nwọn ka (census) kakiri ilẹ Nigeria.

### Ile Igbimo

Ọrọ rẹ na fẹ bi'ge b'adubi, nitoripe bi o ti nsọrọ na ni ẹnyin-oju gbogbo awọn ikọ Ipinle Ijọba Ila-Orun ni Ilu Ibo pọn bi ẹsẹ-ina, ti ara si nta olukulu-ku nibiti nwọn joko si; nigbati awọn ara mi, awọn ikọ lati Oke Ọya (ilu awọn Hausa) ri eleyi, nwọn sare pe awọn ọlọpa wa pe boya ijangbọn le bẹ silẹ. Ni iṣẹju akan, ọga Ọlọpa ti fi moto-akẹru mẹfa ko awọn "bolebajẹ-kobajẹ" Ọlọpa wa, nwọn si yi ile Igbimọ na ka pẹlu ibọn lọwọ wọn.

### Akole-eke

Alhaji Waziri Ibrahim ni Akọle-eke (Forgery) pẹlu ki a ko ikan-mọkan pọ ninu awọn enia ti nwọn ka ninu ilẹ Ijọba Ila Orun ni ilu Ibo. O ni nwọn ṣe eleyi ki nwọn ba le ma ri nkan ponla ni. Alhaji Waziri Ibrahim ni ọlẹ ati froju ni o mba awọn alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ja ni Ibadan. O ni ninu gbogbo ọna mejilelogota ti awọn yan fun wọn wipe ki nwọn fi ka awọn enia ipinle wọn, ọna marun pere ni o yanju nibẹ.

Awọn Olotu Ijọba na ti da lohun wipe irọ ni Alhaji Waziri pa mọ awọn ati pe awawi ni gbogbo ọrọ rẹ na. Iyoku di ọsẹ ti mbọ.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 22 Kosoko Street Lagos Box 167 Phone 2330 EDITOR (OLOTU) OLA ONATADE
15, Kosoko Street, Lagos.